# OTITỌ MARUN



# TO YE FUN Ọ LATI MỌ

1. **Idajọ Ọlọrun Niyi!**

"Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Kò si ẹniti iṣe olododo, kò si ẹnikan. Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun" —Romu 3:10, 23.

2. **Ijiya Idajo Ọlọrun Niyi!**

"Nitoripe iye awọn ti mbẹ ni ipa iṣẹ ofin mbẹ labẹ ègún: nitoriti a ti kọ ọ pe, Ifibu ni olukuluku ẹniti kò duro ninu ohun gbogbo ti a kọ sinu iwe ofin lati mã ṣe wọn"
Galatia 3:10.

"Ẹniti o ba gbà a gbọ́, a ko ni da a lẹjọ; ṣugbọn a ti da ẹniti kò gbà a gbọ́ lẹjọ na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ bibi kanṣoṣo ti Ọlorun gbọ́" —Johannu 3:18.

3. **Ipese Olorun Niyi!**

"Kristi ti rà wa pada kuro lọwọ egun ofin, ẹniti a fi ṣe egun fun wa: nitoriti a ti kọ ọ pe, Ifibu li olukuluku ẹniti a fi kọ́ sori igi"

Galatia 3:13.

"Kristi ti kú nitori ẹ̀ṣẹ wa gẹgẹ bi iwe-mimọ́ ti wi." "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun"

1 Korinti 15:3; Johunnu 3:16.

4. **Asiko To Yẹ Niyi!**

"Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́" —Johannu 1:12.

5. **Ireti Re Kan Soso Niyi!**

"Ẹniti o ba gbà Ọmọ gbọ́, o ni iye ainipẹkun: ẹniti kò ba si gbà Ọmọ gbọ, kì yio ri ìye; ṣugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ lori rẹ̀"

Johannu 3:36.

"Kò si si igbala lọdọ ẹlomiran: nitori kò si oruko miran labẹ ọrun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a le fi gbà wa là"

Iṣe Awọn Aposteli 4:12.

**Word Of Truth**, P.O. Box 1126, Kaduna, Nigeria